

# Iwo gbọ irohin rere na bi?

"Ṣugbọn Ọlọrun fi ifẹ On papa si wa hān ni eyi pe, nigbati awa jẹ ẹlẹṣẹ, Kristi kú fun wa" (Romu 5:8).

"Nitori Ọlọrun fẹ araiye tobẽ gẹ, ti o fi Ọmọ bibi rẹ kanṣoṣo funni, ki ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ̀ má bà ṣegbé, ṣugbọn ki o le ni īye ainipẹkun" (Johannu 3:16).

"Nipa eyi li a gbé fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu wa, nitoriti Ọlọrun rán Ọmọ bíbi rẽ nikanṣoṣo si aiye, ki awa ki o le yē nipasẹ rẹ" (1 Johannu 4:9).

"Ninu eyi ni ifẹ wā, kì iṣe pe awa fẹ Ọlọrun, ṣugbọn on fẹ wa, o si rán Ọmọ rẹ latí jẹ etutu fun ẹ̀ṣẹ wa" (1 Johannu 4:10).

## NJẸ EYI KIṢE IROHIN RERE BI?

"Gbogbo enia li o sá ti ṣẹ̀, ti nwọn si kuna ogo Ọlọrun" (Rom. 3:23).

"Kò si eniti nṣe rere, kò si ẹnikan" (Orin Dafidi 14:3). "Nitoriti kò si olõtọ enia lori ilẹ, ti nṣe rere ti kò si dẹṣẹ" (Oniwasu 7:20).

"Ṣugbọn iwe-mimọ́ ti ṣe gbogbo nkan mọ́ sabẹ ẹṣẹ (Galatia 3:22), ki o le ṣānu fun gbogbo won" (Romu 11:32).

"Gbogbo wa ti sina kirikiri bi agutan, olukuluku wa tẽle ọ̀na ara rẹ̀; Oluwa si ti mu aiṣedede wa gbogbo pade lara rẹ̀" (Isaiah 53:6).

"Eyini ni pe, Ọlọrun wā nínu Kristi, o mba araiye làja sọdọ are rẹ̀, kò si kā irekọja wọn si wọn lọrùn" (2 Korinti 5:19).

"Ẹniti on tikararẹ fi are rẹ rū ẹṣẹ wa lori igi" (1 Peteru 2:24).

"Ṣugbọn a ṣá a li ọgbẹ nitori irekọja wa, a pa a li ara nitori aiṣedede wa; ina alafia wa wà lara rẹ̀, ati nipa ina rẹ li a fi mu wa lara da" (Isaiah 53:5).

## NJẸ EYI KIṢE IROHIN RERE BI?

"Njẹ ki o yé nyin, ará, pe nipasẹ ọkọnrin yi li a nwasu idariji ẹ̀ṣẹ fun nyin." "Nipa orukọ rẹ̀ li ẹnikẹni ti o ba gbà a gbọ, yio ri imukuro ẹ̀ṣẹ gbà" (Iṣe Awon Aposteli 13:38; 10:43).

"Bi ẹ̀ṣẹ nyin ba ri bi òdodó, nwọn o si fun bí òjo-didi; bi nwọn pọ́n bi àlãri, nwọn o dabi irunagutan" (Isaiah 1:18).

"Bi ila-õrun ti jina si iwọ-õrun, beli o mu irekoja wa jina kuro lọdọ wa" (Orin Dafidi 103:12).

"Emi, ani emi li ẹniti o pa irekọja rẹ ré nitori ti emi tikalami, emi ki yio si ranti ẹ̀ṣẹ rẹ" (Isaiah 43:25).

"Ọmọkọnrin, tujuka, a dari ẹṣẹ rẹ ji ọ" (Matteu 9:2).

## EYI, LOTITỌ, JẸ IROHIN RERE!

"Njẹ ẹbi kò si nisisiyi fun awọn ti o wà ninu Kristi Jesu" (Romu 8:1).

"Njẹ bi a si ti nda wa lare nipa igbagbọ́, awa ni alafia lọdọ Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi" (Romu 5:1).

"Kí si işe bẹ̃ nikan, şugbọn awa nşogo ninu Ọlọrun nipa Oluwa wa Jesu Kristi, nipasẹ ẹniti awa ti ri ìlaja gbà nisisiyi" (Romu 5:11).

## NJE EYI PELU KISE IROHIN RERE BI?

"Bi awa ba ngbà ẹ̀ri enia, ẹ̀ri Ọlọrun tobi ju: nitọri eri Ọlọrun li eyi pe O ti jẹri niti Ọmọ rẹ̀" (1 Johannu 5:9).

"Ẹniti o gbà erí rẹ̀ fi edidi di i pe, otitọ li Ọlọrun" (Johannu 3:33).

"Ẹri na si li eyi pe Ọlọrun fun wa ni ìye ainipẹkun, iye yi si mbẹ ninu Ọmọ rẹ̀. Eniti o ba ni Ọmo, o ni iye; eniti ko ba si ni Ọmọ Ọlọrun, kò ni iye" (1 Johannu 5:11, 12).

"Ẹniti o ba gbà Ọmọ gbọ, o ni iye ainipekun: eniti kò ba si gbà Ọmọ gbọ, ki yio ri iye; şugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ" (Johannu 3:36).

"Şugbọn a ti da eniti kò gbà a gbọ́ lẹjọ na, nitoriti kò gbà orukọ Ọmọ bíbi kanşoşo ti Ọlọrun gbọ́" (Johannu 3:18).

**Word Of Truth**, P.O Box 1126, Kaduna, Nigeria